Chief Secretary to the Government

Ọgbẹni Herbert Macaulay ko ku, ara lo fi ti.

# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. VI. NO. 291 SATURDAY, SEPTEMBER 8, 1928. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.

NIGERIA SECRETARIAT 12 SEP. 1928 LAGOS

**White's Radical Gonkiller.**

:o:

(NATIVE.)

[*A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.*]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs**, and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[*Fun Atọsi lailai ati titun.*]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si nję ki o ri aye wu arun mi silę.

Allen 1/5
[illegible]

# To Stop Your Aches & Pains

## Simply Use




For more than 40 years Sloan's Liniment has been used throughout the World. It is kept handy in many thousands of homes to give quick, warming relief from the pains and aches of Rheumatism, Lumbago, Neuralgia, Sprains, Bruises and other severe pains. No need to rub Sloan's—it penetrates and kills the pain instantly.

*Sold by all Dealers.*

Wholesale:
FASSETT & JOHNSON, Ltd.
86, Clerkenwell Road,
London, England.

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILĘ NI OWO GBIGBA RĘ.

| Eko. | | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ę fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

KITOYI.

Iwe-Irohin Ijọba ti ọgbọn ọjọ oṣu *August*, tokọja sọ ti mimu Dr. Caulcrick kuro ni nu Ajọ Igbimọ Aṣofin Ọba nitori ẹbi ti Adajọ Kotu kekere da ni ọjọ *Monday* ọsẹ ti o kọja ; a gbọpe Ọgbẹni ti ṣe iwe Apili ọjọ rẹ yi ni Kotu Gauran eyiti Adajọ Agba gba pe ki nwọn wa tun ro niwaju on.

ITUMỌ EYI Ę JARE.

Adajọ Agba kọ titun ẹjọ Ọgbẹni Macaulay ro niwaju on ni ọjọ *Monday* ọsẹ yi ni a sọpe Adajọ Agba kọ riro ẹjọ yi, lẹsẹkanna ni Adajọ kekere da t'on ati Ọgbẹni Dr. J. A. Caulcrick lẹbi si.

Eyi ti jẹ o?

---

DUNIYAN—LABARI.

[ LATI ỌWỌ KEKERE-AWO. ]

---

YE PARIPA!

Ni irọlẹ ọjọ Alaruba to kọja yi ni ọmọde-binrin kan ṣe alabapade agbako m to kan lojude ile Ologbe Tom Jones lẹhin ọgba ni ibi ti nwọn nkọ fun *Hall* nisisiyi, ibosi ariwo awọn enia gbojikan nibẹ lọjọ na, ọgala ni awọn ọpa Ọba ti da mọto na duro ni nwọn si rọ sinu rẹ, ryẹ-riyẹ o di iwaju aje, ki Ọlọrun da abo bo olukulukn wa lọwọ jamba ile, jamba ode—amin.

KOBOYEYE STREET.

Ki lo ṣe ti adugbo yi le kun fun idọti baun? tabi horo ti o jẹ ni? ki awọn ẹniti o nlo idọti si horo na ṣọra gidigidi nitori aibamọ.

EGERTON ROAD.

Awọn ti nwọn ntẹ Titi ọna Bishop Street, ti pari ibẹ, nwọn si ti bọ si a ti tun Titi Egerton Road ṣe, ni Alakoro loju Titi ibiti awọn ibusọ Oke-arin gbe wa, ki mọto, kẹkẹ-ologere ati mọto alupupu, ma rin ma yan tanda ni Titi iwọnyi lo ku —*Town Council* ẹ ku iṣẹ o.

ASEKO TO OGONGO NSUNRAKI.

A ri iwe ikede lode ni ọjọ Satide ijẹjọ pe didibo fun awọn Aṣoju mẹta Eko yio ya ni ọjọ kejidinlogun oṣu yi, o ku ọjọ mọkanlelogun loni.

Ibo didi na yio bẹrẹ ni agogo mẹjọ owurọ di ọsan ati ni agogo kan ọsan di agogo mẹrin irọlẹ, ni ile Afari-oguu Lẹhingbẹti *Glover Memorial Hall* gẹgẹ bi atẹhinwa—awọn ẹniti o ti fi orukọ silẹ ni o le dibo fun awọn ẹniti yio lọ si Igbimọ-Aṣofin na gẹgẹ bi iwe ikede ti wi.

ỌLỌLA GOMINA.

A nreti dide Ọlọla Gomina wa. Graeme Thomson, K.C.B., G.C.M.G., ati awọn ti o ba a lọ ni ọjọ mẹrin Atalata.

ẸGBẸ DẸMỌ.

Ni eyiti iwe-ikede ti jade fun lati yan awọn Aṣoju mẹta ti Eko si Igbimọ-Aṣofin vi *Legislative Council*, iṣẹ de fun awọn ọmọ-ẹgbẹ Dẹmọ lati ṣe papa fun awọn ẹniti o ti ni orukọ nlẹ lati le yan enia.

OJOJUMỌ NI ALAṢỌ OSUN NṢỌ 'ṢẸ.

Ni owurọ ọjọ *Monday* ọsẹ yi, ni a gbọ wipe mọto ṣe ọlọpa kan ni jamba ni a ti gun kerewi Iddo ; eyi ha nkọ, Ọlọrun Ọba, dakun jare, lọwọ orişrişi jamba mọto wọnyi.

LỌWỌ ỌTA-ILE, ỌTA-ODE, OLUWA RERE GBA WA.

Awọn agbagba lo ma npa owe kan, nwọn ni bi iku ile ko pa ni, ti ode kole pa ni ; bi ẹnikan ba ni ọta gidigidi ti o rọgba yika lọtun ati losi, dajudaju a o tun ma ri lara wọn ẹniti oluwarẹ npe ni ọrẹ ti yio tun ma ṣe ilara oluwarẹ lati ma fi aşiri ọrẹ rẹ han awọn ọta irufẹ awọn eni bẹ ni owe wa na nba wi pe : bi iku ile ko pa ni, ti ode kole pa ni.

Nigbati lasigbo kan ba şeşi de ba ni, nigbana ni awọn ọta ile ma duro bi ọta ode, ni awọn ẹniti oluwarẹ npe ni ọrẹ timọtimọ fun on yio di ọta ode tabi ọta pataki fun oluwarẹ ti nwọn yio si ma gbe ikọkọ ati iba fi apa janu si oluwarẹ, nigbana ni

olukuluku awọn ara, yio fi ara wọn han gbangba bi ẹniti o nba ni ṣọta ti o si nfi ọwọ janu si ni, ti nwọn yio si ma yọ ṣuti si ni, ni orişirşi ede ti ko ni lari—şugbọn nigbati iwọ ti o npe ara rẹ ni ọrẹ timọ-timọ nigbati iwọ nri anfani pataki jẹ ti onjẹ ojo rẹ ko si dinku nigbana ti o ba tun wa pada nfọ edekede jade lẹnu nibo li iwọ yio ru u wọ? iwọ nyọ, iwọ fi ọwọ janu iwọ ọta-ile iwọ ha ti gun igi ri ẹhin aiye na?

## Ẹ O JẸKI A TẸWỌ ADURA.

Ko si iṣẹ, ko si owo, ko si alafia onile yi ko mọ ohun ti onile yi nṣe, olowo nke, talika nke, a ha tun le sọ ti awọn akuṣẹ mẹ, ẹniti Ọlọrun ba jaja şe fun ti o nri torọ-kọbọ da ẹkọ owurọ o di ki o ma şe *Alihamdu-li-Lahi*, a dupẹ lọwọ Sati, bi enia ba -dide larin Eko yi loni pe on nfẹ ya tọrọ-kọbọ lọwọ ẹnikan, nigbati o ba ma yida gbogbo ilu yi ki yio ti ri kọbọ kan şoṣo ya ninu tọrọ na, ikun imu rẹ ti ọtun yio bo si ti osi, a ha fi eyi purọ bi ẹnikeji? a fi ẹniti o ba ni ohun iduro ti o duro giri bi "I" ni o le ri kọbọ meji ya, ki isi iṣẹ wipe nitoripe oluwarẹ ti gbojule ohun ti yio fi duro ya owo, nitorina nkọ, yio ri owo na ya ni irọwọ-irọsẹ, irọ funfun patapata gba laiye ni, oluwarẹ yio rin titi agara a fẹrẹ da, on papa yio ke şaba, wahala ti yio şe ki o to ri owo ẹni ọhun, yio fẹrẹ ju ohun ti o fẹ fi owo na şe papa lọ—kilo fa sababi yi, loju wa o dabi ẹnipe o wu Sati bẹ fun wa ni, nitori iwa ẹşẹ ati iwa irira, iwa ole, iwa abinuku, iwa ọtẹ, iwa afoju fẹni ma f'ọkan fẹni, iwa bi o ba ki o mu, iwa bi o ko ba ki o bu lẹşẹ, iwa mu 'ri maşe fi silẹ, iwa keta iwa ijẹri-eke si ọmọ ẹnikeji ẹni, iwa ole, iwa agbere, iwa panşaga, iwa gbigba owo-ele ati oniruru iwa buburu gbogbo bawọnni ti ọpọlọpọ awọn ọmọ Anabi Adamọ nhu.

Lori gbogbo iwa aişedede bokanna ki nwọn rẹ owo rẹ silẹ npele lo tunbọ npele si, iwọnyi ko ha to ohun ti o le fa sababi gbogbo rudurudu yi; şugbọn Ọba Ọlọrun ki işe Ọba ika Ọba ti a npe ti o ngbọ ni, nitori na ẹ jẹki a tẹwọ adura si I boya awọn Mọlayika a jẹ şe amin, ki Kiriyo pe Jesu, ki Imale pe Mọmọdu, ki awọn Abọrişa pẹlu pe mọlẹ ti wọn lọna ti wọn, ki olukuluku tẹwọ adura nisisiyi ki a ma şe "Raba-na Agfiri lana nwa-wa tari-amu-na iwa-ka Gafuru Rahimu-amu bi jayi Fatiha, bi aşa awọn ara bi.

## ỌGA-GUN RUXTON.

Gẹgẹbi iwe akiyesi kan ti a ri lode, Ọlọla Ọga-gun U. F. Ruxton, C.M.G., yio şe sugaba fun wọn ni ibi ere aladun kan ni Ile Afari-ogun *Glover Memorial Hall* ni ọjọ Alaruba ọjọ karun oşu yi; awọn oyinbo meji tọtọ ati awọn enia diẹ yio wa bi ere aladun na.

## SUGABA!

Awọn jakanjakan yio şe ere pataki kan ni Ile Afari-ogun ni ọjọ keje oşu yi ti nşe Jimọ: Ẹniti yio şe Şugaba ere na ni ana ni Dokita J. A. Caulcrick, M.B., ch.B.

## DOKITA KỌLKRIKI.

Gẹgẹ bi Iwe-irohin Ijọba ti a gbọ wipe o jade ni ọjọ 30, August 1928, da Dokita Caulcrick duro ninu Igbimọ-Aşofin *Legislative Council* gẹgẹ bi ọkan ninu Aşoju mẹta fun ilu nipa idajọ ti kotu Ọlọpa da a ni ọjọ kẹtadinlogun oşu August.

## IPADE ẸGBẸ DẸMỌ.

Ipade Bombata mbẹ fun Ẹgbẹ "Democratic Party" loni ni ile Afari-ogun *Glover Memorial Hall* ni abẹ Alagba Ọlọla Lọya Eric O. Moore ati awọn ojoye oni Fila funfun ati awọn Abagbọn.

Ki ẹşẹ gbogbo ọmọ ẹgbẹ pe şan-şan, işẹ pataki mbẹ lati şe papa nipa şawura yiyan awọn ẹniti nwọn o fẹ lati le dibo fun ninu oşu yi.

## "MA BINU ORI."

Gẹgẹ bi iwe akiyesi awọn mẹmba obinrin kan ti Şọşi Wesleyan Olowogbowo yio şe ere pataki kan ti o njẹ "Ma binu ori" ni ile *Glover Hall* Lẹhingbẹti ni ọjọ Alamisi ijẹta labẹ alagba Ọgbẹni Councillor J. Bagan Benjamin, C.E., ni gasikiya a kole binu ori ki a fi fila dedi.

---

## NIGERIAN DAILY TIMES SỌ PE, A NI LATI PA ẸNU HERBERT MACAULEY MỌ!

**Herbert Macauley must be gagged**

---

Iwe akọle yi ni oniwe irohin ojojumọ Nigerian Daily Times kọ sinu iwe rẹ ti ọjọ kẹta oşu August 1928, eyiti gbogbo ilu ka ni aka ye, ti wọn si ri ohun ti oniwe irohin na kọ pẹlu ifi ọkan balẹ lai si ohun kan ti o si da ẹru ba ni wipe ọmọ enia ni a ni ki alaşẹ pa ni ẹnu mọ eyi ara! wọn ni bi ko ba ni idi, oju ọrun to ẹiyẹ meji fo, la lai fi ara kan ara, şugbọn nigbati ọgbẹni Herbert Macauley ni ọna tirẹ to ngba ti oniwe irohin yi si ni ọna tirẹ pẹlu bakanna, ko yẹ ki wọn fi ara gbun ara, nitori oni kaluku ni ọgbọn tirẹ ninu.

Ni ọjọ Monday ijo kẹtadilọgbọn oşu August 1928 niwaju Adajọ Kotu ọlọpa ọgbẹni H. A. Young K.C., ni nwọn da ẹjọ ọgbẹni Herbert Macauley C.E., wipe kio lọ si ẹwọn oşu mẹfa ati pe Ọlọla Dokita Caulcrick kio san adọta pọun tabi ẹwọn oşu mẹta gẹgẹ bi mo ti ka ninu Daily Times ti 28/8/28 şugbọn bo jọ gate ko jọ gate ofi ẹşẹ mejeji tiro nitori bi enia ti wun ko wa ninu aiye yi ohun to ma şe ko ni şe alai şe lẹhin na ohun ti ani lati mọ ni pe ohun gbogbo nlọ fun rere. Bo ba jẹ ohun ti ko wun Ọlọrun ni şişe, ole fi si ọkan ọgbẹni Adajọ Young pe Alaga, ẹniti a fa wa si iwaju rẹ lati fi şe ẹlẹya loju awọn enia buburu ti wọn nwa işubu rẹ palaşẹ wipe ohun ti a mu fun

ko to ohun ti a le jẹ ẹ niya si nitori pe ko da orukọ ẹnikẹni nipa ohun ti wọn mu fun nitorina da silẹ wipe ko ma lọ. Ṣe bẹ lo si ma ri, gbogbo ohun to ba ṣelẹ lati ọdọ Oluwa ni. Ṣe enia lo sọ gbangban lalai fi ẹnu si kọrọ wipe ohun ko fẹ ki Ọba wa Eşugbayi ko wa si Eko yala oku rẹ ni tabi aiye rẹ, enia lo si tun sọ pẹlu wipe bi ohun ba ri nkan ti ko ni jẹ ko wa si Eko mọ, on aşe iranlọwọ si irufẹ bẹ ni ero ti wa ẹniti a ba nba nọja ni a nwo, a ki wo ariwo ọja. La lai si tàbi tabi Adajọ fi Ọgbẹni Herbert Macauley si ẹwọn oşu mẹfa şugbọn eyi ko ba ẹgbẹ Democratic Party jẹ nitori pe lotọlotọ ni ọgbẹni wa Macauley jẹ olotu ẹgbẹ yi, Ọlọrun Ọba to ba wa ko ẹgbẹ yi jọ yio si wa pẹlu rẹ titi o ma fi de ilẹ yi. Lotọ ohun to şelẹ, yi o ba wa ninu jẹ lọpọlọpọ fun asiko diẹ ti yio kuro ni arin wa afo rẹ yio şi silẹ, şugbon Ọlọrun rẹ tabi Ọlọrun tiwa ko lọ ninu ẹgbẹ yi. Ninu gbogbo awọn enia ti wọn nyọ loni yi, tani o ma sọ wipe lọna ti a ngba bi enia laye ni idi iya tabi idi baba ni, ti a ma fi itın tirẹ we ti Ọgbẹni Macauley yi, ki asi sọ nipa ẹkọ mimọ ẹ o si ri wipe ohun ti a bi ọgbẹni Macauley mọ, ẹlomiran wa ni ode Eko loni ti igba aiye rẹ si ndun bi Sugar ti osi ro wipe ko si nkankan ti ole fi iya jẹ on, a lai mọ kan. iwọ ko ha bi ọmọ silẹ ni aiye ti iwọ yio si fi silẹ ni ọjọk an, ti ilẹ ọjọ miran yio si mọ ni ẹhin rẹ ni ọla, ti igi ti iwọ lẹ silẹ ni ilu ti yio wa hu ti ọmo re yio si ma ka eso rẹ, iwọ ti iwọ ko ni omọ nilẹ iwa to wun ko hu ni aiye yi, iwọ yio jihin rẹ ni ẹhin ọla.

Bi ẹyin ti ngbero lati gbe alagbara şubu ẹyin ha gbagbe wipe Ọlọrun si ti gbe ẹlomiran jade ti yio şe bakanna ti gbogbo aiye yio si ma ri wipe eleyi wa lati şe ododo, ko si ni boju wo ẹhin lati şe eyiti Ọlọrun fi si agbara rẹ, nitori na ẹyin Igbimọ wa ẹ duro şinşin lai yẹ ẹsẹ, Ọlọrun yio si wa pẹlu yin nigbagbogbo Amin.

Gbogbo wa lo gbọ nigbati iwe aşẹ Ọba King George ati awọn Igbimọ rẹ fi ọwọ si, eyiti w n si fi si Kotu ni ọjọ Alamisi to koja nipa ẹjọ Ọba wa Eşugbayi Eleko, gbogbo iwe irohin nilẹ yi lo tẹ iwe aşẹ na aya fi Daily Times, Nigerian Pioneer ti a ko ri ninu rẹ şugbọn Eleti Ọfẹ ko jade a ko si ti wo Nigerian Spectator to ba wa ninu rẹ, nipa eyi gbogbo enia ni yo mọ wipe gbogbo agbaiye lo nfẹ Ọba wa yi wipe ko pada si ilu rẹ, nipa eyi wọn ni ibi ti enia ba nlọ lo ma kọju si, bi enia ko jẹ ara ile oni lati jẹ ara ita, şugbọn enia ko le jẹ ẹni ile ko si tun ni on ma jẹ ẹni ita pẹlu o şoro nitori pe ko si ohun ti eti ko gbọ tan lẹnu awọn alai mọ kan, wipe ni eyi ti awọ tẹ ọgagun ẹyin ọmọ ẹgbẹ ẹ ko wa ni wa ibi gba bayi, şugbọn eyi dara ko ma ti ẹnu wọn jade bayi nitori pe bi enia meji ba ja ẹnikan lo ma da ẹnikan iyẹn ko ni ki agbo fọ, şugbọn kini ni asiko ti ija Mọşalaşi oni iye igba ti ijọba Mọşalaşi Jimọ nbọ si apa kan lọwọ titi şugbọn nigbati Ọlọrun Ọba adakẹ dajọ ma fi opin si opa laşẹ lati ẹnu Adajọ Ọgbẹni Ọlọla Fredrick Alan Vander Meulen wipe ewe ti Erin ba tẹ ki gberi nitori na ni atoni lọ ni awọn Janma ti ni ẹtọ si Mọşalaşi na ti wọn si ntọju rẹ ti wọn ko si le ẹnikan tabi ẹnikẹni wipe ki wọn ma wọ inu re la ki irun fun ẹlẹda wọn, aya fi awọn wukuwuku ti wọn nba fitting Mọşalaşi na jẹ ti wọn si le kuro nibẹ, nitorina ki ẹyin ti ẹ nwa işubu ọmọ alakeji yin wipe ko si ohunkohun to le da ẹjọ Ọba wa Eşugbayi Eleko duro yala Macauley wa nile tabi ko si nile, nitori awọn ti ẹjọ yi wa ni ọwọ wọn, ko rẹ wọn Ọlọrun majẹ ko rẹ yin, ko si si ohun kan to le ba wọn ninu jẹ depo wipe ki wọn da ẹjọ yi duro, ati pe Lọya to ma ro ẹjọ yi owa nilẹ, iwe ẹjọ yi si ti de ile ẹjọ, nitori na ẹyin enia wa, ẹmu eti yin kuro ninu isọkusọ gbogbo wọn yi, on ti ẹ nşe ni ki ẹ kọju mọ. Ọpọlọpọ le sọ wipe wọn tun jẹ Ọba miran si Eko bẹni ẹyin Dẹmọ si ni Ọba King fi ọwọ si iwe aşẹ yin, njẹ iwe aramu kọ ni ẹ ngbe kiri, Ọba to fun yin ni aşẹ wipe ki Ọba Eşugbayi tun ẹjọ rẹ ro, Oba na lo si fun Ijọba Eko ni aşẹ wipe ki ẹ jẹ Ọba mi, ẹyin alai mo ye, aya fi bi ohun ti ẹyin ba gbin ti ki ba nhu, aya fi bi o ba ku Lotọ ni mo wi fun yin, iwe aşẹ de wipe ẹjọ Ọba wa Eşugbayi Eleko ni lati di ti tun ro niwaju Adajọ miran ati wipe Adajọ to ba ma gbọ ni lati gbọ gbogbo kulẹkulẹ rẹ, nitori na awa ko le sọ ireti nu, nitori wipe ibi ti ẹjọ na de yẹn bi aba bolẹ bọ ibẹ ẹjọ wa ku niyẹn şugbon niwọn igba to wun Ọlọrun lati wipe ẹjọ na ni lati di riro o fi aşẹ yi si lati ẹnu Alayeluwa King papa osi fi aşẹ si. Eyiyi lo wa to ayọ.

Lọna keji, ẹ tun bere pe nigbawo ni Ọba yin yio ti Ọyọ bọ, bẹni fun ẹniti ofun wa ni ireti pe ki wọn tun ẹjọ rẹ gbọ awa ko kanju, nitori oni Psalmu ti wipe "Maşe ikanr nitori awọn oluşẹ buburu, ki iwọ kio ma şe ilara nitori awọn oniṣẹẹşẹ" ninu eyi bi Ọlọrun Ọba ti o da orun ohun aiye ti o ba si pa wa mọ titi di igba ti ẹjọ na yio fi fi ara ti awa o ma reti, nitori ateni-meni ko le to atana-mana adura wa ni lojojumọ wipe ki Ọlọrun şa da ẹmi Ọba wa Eşugbayi Eleko si lọhun titi ẹjọ rẹ yio fi fi ara ti sọkan, Nitori Ọba lo mọ ẹjọ da. Awọn ẹniti Ọba wun lati jẹ wọn ni lati jẹ nitori ibi ti enia ba nlọ lo nkọju si, eyiti o ndun wa ni awa nran yi eyiti osi wa ni ẹmi tiwọn ni wọn nran, ki Ọlọrun jẹki gbogbo ere mejeji yọri si rere. Ẹmi lajulọ.

Nipa ọrọ ọgbẹni wa Herbert Macauley ni mo tun pada si, ko si oşelu kau ti oju rẹ koni ri lasigbo aiye, ẹlomiran le ni on fẹ lọ si Igbimọ Aşofin tabi Igbimọ Munisiba nigbakugba şugbọn ti ibo ti gbogbo ilu ndi fun wọn ti tirẹ ko to ti awọn enia yoku, ti osi rope awọn kan ni ko fẹ on, şugbọn o gbagbe wipe bo ba jẹ ohun ti Ọlọrun fẹ fun ni oni lati wọ Igbimọ na, şugbọn nigbati Ọlọrun rẹ ko fẹ, o wa le fi ikanra mu ẹnikẹni wipe awọn lo şe o—iwọ ko mọ wipe ori rẹ buru ni ati

pe bi ori rẹ ba dara Ọlọrun a ran awọn enia rẹ siọ lati ṣe alati lẹhin fun ọ. Ni oṣu to nbọ ni a ma dibo fun awọn ẹniti wọn o yan lọ, nitori ẹniti o ba fẹ lọ ko fi si adura wipe bi oti jẹ aniyan on lati ṣe ore fun ilẹ yi ko ma ṣai jẹ ki ori on ko wọ Igbimọ nla ẹniti yio dibo fun enia kio si fi si ero wipe oju saju ko si, ẹniti Ọlọrun on ran on si ni on ma di ibo fun. Nitori na ọrọ Macauley yi ki ṣe on iyanu fun ẹnikẹni ṣe koji owo, enia ni Lord Terrington ti o jale ti o si wọ ẹwọn ọdun mẹrin ninu ọdun ni, oju wa ni ti Horatio Bottomley ni ilu oyinbo o ṣa ti jade, ko si ẹniti ko ni iya tirẹ ni aiye ẹwo Jesu papa ẹ gbọ bi St. Luke ti wi

> "Nigbana li o pe awọn mejila sọdọ rẹ, osi wi fun wọn pe, sa a wo o, awa ngoke lọ si Jerusalẹmu, ao si mu ohun gbogbo ṣẹ, ti a ti kọ lati ọwọ Woli wa, nitori ọmọ-enia. Nitori ao fi i le awọn keferi lọwọ, ao si fi i ṣe ẹlẹya, a o si fi ṣe ẹsin, ao si tutọ si i lara. Nwọn o si na a, nwọn osi pa a. Ni ijọ kẹta yio si dide. Ọkan ninu nkan wọnyi ko si ye wọn: ọrọ yi si pamọ fun wọn, bẹni wọn ko si mọ ohun ti a wi:—

Ọrọ ọgbẹni Macauley o nkọ wa ni ẹkọ wipe ibi ti a ba duro si ki ama yẹ sẹ ki ohunkohun ti oma wa ba oluwa rẹ mbẹ kio wa ba, nitori ohun gbogbo ko ṣẹhin Ọlọrun, nitori na ẹyin ọmọ Ẹgbẹ Democratic ẹ duro ṣinṣin lai yẹ sẹ nitori ere yin nbẹ niwaju Oluwa. Nigbati asiko ati dibo yio ba de ẹ o gbohun kan rere lati ju, ẹfi eti silẹ gbogbo ṣiṣe nbẹ lowo Oluwa. Ọpa Igbeleka tẹhin loju. Bi oniwe irohin Daily News ti wi ni ọjọ Tuesday ijọ keji ti iṣẹlẹ nla ṣẹ ti ikele aṣọ ọrun si ya ti o wipe "Ọbẹ nba ile ara rẹ jẹ oni On nba akọ jẹ" owe ni o. Bi Macauley wa ni ile ẹniti ẹgbẹ Dẹmọ ma yan ni won ma yan, bi ko dẹ si ni ile ẹniti wọn ma yan ni wọn ma yan—ki olotọ ko pẹ—ki oṣika ko pẹ ṣugbọn ilẹ lo ma mọ ẹniti yio tẹ on pẹ. Abọ re o—Otun di ọsẹ to nbọ lagbara Baba.

Emi ni ti nyin nitotọ,

ENIA KO DA BI ALLAH.

## DIDE FU, DIDE.

LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete.*

Mo bẹrẹ f'oji,

Iṣẹ de fun awọn ara ilu papa awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ lati ṣṣe nisisiyi nitorina li a tiṣe kigbe wipe dide fu dide.

Aseko to fun ilu lati yan awọn Aṣoju ilu wa mẹta si Igbimọ Aṣofin *Legislative Council* gẹgẹbi o ti jẹ wipe ni ogunjọ oṣu yi ni yio di ọdun marun gbako ti awọn ilu papa ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ti Ebute ti dibo fun awọn Aṣoju mẹta ni ile Afaṛi-ogun *Glover Memorial Hall* iṣẹ ti awọn mẹta ti o ti wa nibẹ ri lati ogunjọ oṣu September ọdun 1923, ni lati kasẹ nilẹ ki a si jẹki awọn mẹta miran tun gba 'ra di ni ọjọ mejidinlọgbọn oṣu yi, ti nwọn yio si tun ma ba iṣẹ ilu lọ bakanna.

Ṣugbọn siwaju akoko yi, ni a ni lati mọ oju ẹniti o fẹ lọ, ki ilu ba le mọ wọn lati dibo fun, ani ki nwọn le mọ ẹniti o wu olukuluku wọn lati dibo fun.

Bi awọn ti o tilẹ fẹ ki nwọn yan on si Igbimọ Aṣofin tilẹ ṣokunkun fun wa mọ nisisiyi, awọn fun ara wọn yio ti ma gbaradi lati yọju si ita titi igbana, ọran 'yan ni eyi jẹ nitori nwon ki yio ṣe ai ṣe iwe ikede oruko wọn si ode pe ki nwọn dibo fun awọn; awọn ẹniti o si ni lati dibo gbagba-gba ni oju wọn ti wa ni ọna nisisiyi, awọn ẹniti ko si le r'ọwọ yọ gbe ibo didi ẹwẹ nwọn ti nwoye ẹniti awọn ẹgbẹ Dẹmọ tabi awọn ẹlomiran dede yio dibo fun.

Boya a ki yio tun ṣe alai ri awọn ẹlomiran ti nwọn ma fi oruko wọn si ode lai rotẹlẹ ti nwọn ma fẹ ki ẹnikẹni dibo fun wọn, ṣugbọn ẹniti o ba ma fi ọwọ si iwe kẹ ma ni a ri wipe yio le dibo fun awọn ẹniti yio fẹ lati lọ si Kansulu na, yala awọn ẹniti ẹgbẹ Dẹmọ yio mu tabi ti awọn ẹlomiran yio fẹ ki o le lọ lara awọn ẹniti ko ni fẹ fi ti ẹgbẹ Dẹmọ ṣe gẹgẹbi awọn ẹlomiran ti ṣe ni ọdun 1823 ati ni ọdun 1926, ṣugbọn awa ko ro wipe awọn ọmọ ẹgbẹ Bombata kọ ẹnikan lati dibo fun, bi oluwarẹ ko tilẹ wa lara awọn ẹgbẹ yi ṣugbọn ni iwọn igbati o ba ti kan si awọn ẹgbẹ na pe ki nwọn fa on ni tẹtẹ wọ Kansulu, bi eyi ko ba ri bẹ ṣa ni a ko le sọ.

Ni ero ti emi bi ẹnikan ba fẹ dibo fun ẹnikan yio fẹ ki on ri yẹkini bi oluwarẹ ti ṣe ni lati lọ daradara ani yio fẹ ki on mọ ẹniti o nran oluwarẹ lọ tabi iṣẹ ẹniti oluwarẹ yio ma jẹ lọhun, nitori agbajọ owọ ni enia fi nsọ aiya, enia o kuku ni sọ wipe nitori aye wa nilẹ fun ẹnikẹni lati lọ si Kansulu ki oluwarẹ kuku bẹrẹ si sọ wipe dibo fun mi, dajudaju oluwarẹ ni lati woye daradara ki o to le di irufẹ ibo bẹ.

Ipade pataki mbẹ fun awon ẹgbẹ Dẹmọ loni papa lara iṣẹ ti nwọn ni lati ṣe, nwọn o wewe bi nwọn yio ti ṣe idibo ti o mbo yi si, nibẹ ni a ro wipe a o gbọ ẹniti o ba nfẹ ki Dẹmọ dibo fun wọn, ọjọ na lo kusata yi, ọsẹ mẹta lo bo ọjọ loju nigbati a ba tun fi ri ọsẹ kan si lẹhin rẹ ogongo yio sun 'ra ki ọjọ na yio wọle, dibo fun mi! dibo fun mi!! gbogbo rẹ yio ṣe ṣin, ori awọn yio wọ igba ni agogo mẹrin irọlẹ ọjọ Jimọ ọjọ kejidinlọgbọn oṣu yi—nitorina dide fu dide!

## OLUWA JỌWỌ DAKUN!

Ibosi owo ati ibosi iṣẹ ni ogunlọgọ awọn ọmọ araiye nke lode oni.

Nigbati a sorikodo lati yẹ ọran na wo siwa-sẹhin bi o ti nlọ si yi, eyi lo mu wa ṣe adura atọkanwa yi pe "Oluwa jọwọ dakun," boya Oluwa yio ṣi oju anu Rẹ wo wa.

Nipa gidi kilo tilẹ fa ti ai si owo ati ai ri iṣẹ ṣe to mbẹ lode? gẹgẹ bi a ti mọ wipe owo kosi enia ko sunwọn iṣẹ ni ogun iṣẹ, laisi iṣẹ iṣẹ kole tan, enia kole ri owo na, laisi owo lọwọ kẹ enia kole ni lari tobẹ, a fi ti oluwarẹ ba ri ẹniti o nba gbe ẹru ti o si nṣe atilẹhin fun loju mejeji sibẹsibẹ na ko dara fun ọmọluwabi kan ki o wa ki o ma ni iṣẹ lọwọ, bi o tilẹ tun ni ẹniti o jẹ pataki ti o jẹ igi lẹhin ọgba fun u, eyi ko to sibẹsibẹ, nitori bi oluwarẹ ba nbere tọrọ bere kọbọ loni lọla, nigbati o ba di ọjọ kan ti o ba bọ si odi fun ẹniti o ṣe atilẹhin ojojumọ bayi o le wijọ pe họwu tirẹ nikan ni on wa aiye wa ran, iwọ na o ko gbọdọ lọ wa iṣẹ ṣe tabi emi loni ki o ma ri iṣẹ ṣe tabi itumọ ki o ma tọrọ owo lọwọ on nigbagbogbo lai ki iṣe ọnu kokọrọ bi ẹnipe iwọ lo ṣe iṣẹ rẹ si on lọwọ.

Bi a tilẹ ri ẹniti o ri ẹmi rẹ lati gbe e, ki yio ṣai ma di i lọwọ lẹkankan, gẹgẹ bi a ti wi nisisiyi.

Ṣugbọn iṣẹ na ha wa lode tobẹ lati ṣe tabi ko ha ṣoro ati ohun abuku fun enia lati jọye alaifẹ ṣiṣẹ ni iwọn igbati o jẹ wipe Ọlọrun pese iṣẹ fun oluwarẹ lati ṣe, bi o ba ri ẹniti o ri iṣẹ ti ko fẹ, ṣe ki a wo oluwarẹ wo daradara—ani iṣẹ ha wa lode lati ṣe li a nwi yi? agbẹdọ kosi, kini a nwo ti a ko ji giri si eyi, a nwo ko kan mi, ko kan mi, gẹgẹ bi ko ti kan ẹlomiran lo njẹ ki a ma ri ọpọlọpọ ọmọ gbajumọ tabi ọmọ olowo miran ki o ma rin ni idọti lode ti a si nri ọmọ talika miran ẹwẹ ti o si nmọ fefe bakanna.

Ọpọlọpọ ibanujẹ pẹlu arẹ ọkan aisi owo ati aisi iṣẹ bẹ ọgọrọ enia lode ti a wa nisisiyi nigbati o jẹ wipe nwọn nwo ararẹ wo pe on ti on ti nṣi ṣọbu nkan meremere, tabi awọn nkan pataki dede ti o nsọ enia di ọlọrọ tabi olowo, ti o si nri owo na fa bi on ti fẹ tobẹ ti on le ma gbe bukata ọgọrun enia, ti on nri dukiya lo, ti on si wa di ẹniti o tun nfi ọkan nyi ọkan ki on tole jẹun si ẹnu ani on ti on ti nmu ti *tea* lararọ ati ni alalẹ bi awon oni 'kan papa si tun wa di ẹniti o nmu ẹkọ tabi ti on tun di ẹniti o tun nda kọko tabi dẹngẹ mu.

Ọpọlọpọ awọn oni ṣọbu nla nla to tun pada di ẹniti o tun nlọ si ọdọ awọn oyinbo-onṣowo pẹlu nkan ohun-ini won ki nwọn to le ṣe ọmọ enia tabi ki nwọn to le ri ọwọ yọgbe diẹ bi koṣe ẹniti Ọlorun ba ti kadara ni ori olowo tabi ọrun rẹ.

Ani ọpọlọpọ enia lo di ẹniti a nsin ni owo tabi ti a nranṣẹ si pe ki o wa balu si, nipa ọwọ-olowọ ati ẹsẹ-ẹlẹsẹ ti o fi ngbe'ra, tobẹ ti o jẹ wipe iba tọrọ kọbọ ti yio jẹ ti oluwarẹ yio ti di ohun ti awọn alagbeda yio tun gbe wọ igbo lọ. bẹ bi enia ko si nta ọja kan lawin lode ti a wa yi o ṣoro fun oluwarẹ gidigidi lati le ma ta ọja rẹ bi o ti fẹ, ninu ti ararẹ tabi eyiti oluwarẹ jaja ri ẹni ta fun on lawin na ni on papa tun ni lati tun ta ni awin bakanna.

Ni ito ti ilẹ yi to loni, ṣaṣa ni ile ti Agamandi rẹ wa lọwọ oluwarẹ, nibo ni awọn iyoku mbẹ? nwọn ti ba gbese lọ omiran kẹsi mbẹ ni sakani awọn oyinbo oniṣowo, tabi ni nwọn ti gbe dogo.

Kosi ẹda kan ti yio ji ni arọ ọjọ kan, ti ko si ri iṣẹ kan ṣe ti ọkan rẹ le balẹ nitotọ tabi ti inu rẹ le dun, bi oluwarẹ ba tilẹ jẹ ẹniti o ngbo bukata ọpọlọpọ enia, yio fẹrẹ le ri imi adiẹ ki o pe ni owo, nigbati a ni owo lowọ ni oluwarẹ nsọ wipe kosi bi on ko ti jẹ, nigbati a nri owo nna, li a nsọ wipe a nṣe gbajumọ ti a nfogan wipe emi ni mo wa nibẹ, nigbati a ni owo lọwọ ni ẹlomiran nda ile haya fun awọn alapamọ nigbati obinrin omiran nri owo lọwọ ẹni ni nwọn ngbọn ṣoṣo mọ ni, ni ọkunrin papa nfi aṣọ loju lalẹ nle'mu kiri bi obukọ nigbati a ni owo lọwọ li a nkakọ fun awọn ẹlẹyinju-ẹgẹ ti awọn ẹlomiran ko jọ sile pe akọ ẹja, kuta olodo, ẹfua, igbakẹrẹ tabi awọn ẹja pataki gbogbo bẹ ti o gbe ehin dada ni on fẹ jẹ ani nigbana ni a ndaba bata ti o pe ati bọsẹ ti o bamu daradara, ani nigbana ni a nranti aṣọ (Complete Suit) ti o lẹ daradara ati fila Ate tabi Hẹlimẹti ti o ṣe rebete. Wayi o lode ti oni ọpọlọpọ awọn ẹniti o nyanbọ akọ ẹja kọ lọ tun di ẹniti o njẹ ẹja—Palapala tabi ẹja abọmafọ ti nwọn Indi sinu apo wa lati ilu oyinbo, ani ọgọrọ awọn ẹniti o ti nyọ getọsi lọ si ibi iṣẹ kọ lo ha tun di ẹniti o tun nlo aṣọ kan lọ si ibi iṣẹ fun ọsẹ kan dipo getọsi ojojumọ, bi getọsi rẹ tilẹ parẹ ki o to to ọjọ kẹji yio run mọ bẹ titi di ọjọ Satide.

A kole ma sọ irufẹ adanwo bẹbẹ ti o ba ogunlọgọ enia ni samani ti a wa yi, ṣugbọn bokanran ki a dide si i, eyiti o ndun olukuluku lo nbaja, ohun ti kole ṣe enia lanfani kan ọpa agbeleka tẹhin loju—Oluwa jọwọ dakun!

Emi ni ti nyin nitotọ,

KEKERE-AWO.

---

Gẹgẹ bi a ti nwi nipa oju-titi Idumagbo ni ibiti awọn Oyinbo nfi agba-epo wọn ti si. Oju-titi na jẹ ohun pataki ti a bẹ ẹnyin Municipal lọpọlọpọ ẹ jọwọ ki ẹ ba ni tun oju-ọna na ṣe laipẹ yi; o mba enia laṣọ jẹ lọpọlọpọ. ko dara fun motọ ati Basikulu, enia papa ko le kọja, a bẹ awọn ọga Municipal lati ba ni fi oju si ọna na ati ba tun ṣe laipẹ yi o.

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, SEPTEMBER 8, 1928.

## HERBERT MACAULAY KO KU, ARA LO FI TI.

Lati igbati idigbolu aiye ti ba Ọgbẹni wa Herbert Macaulay ni o dabi ẹnipe gbogbo ilu wa ninu Ọ̀fọ̀ eyi ko le ṣe ki o ma ri bẹ, nitoripe iṣẹ ribiribi ti o nṣe fun rere ilu Eko yi; papa fun Idile Ọba Dosumu nipati ọran *Prnice* Eṣugbayi Eleko ki ṣe iṣẹ kekere tabi iṣẹ ti ẹnikan le fi ọwọ yẹpẹrẹ mu; ẹ si wa wo akoko igbati nkan yi ṣẹlẹ si, ti o jẹ asiko ti Ijọba kesi ilu pe ki awọn ti nwọn ti dibo gbaradi lati yan awọn enia mẹta miran si Ajọ-Igbimọ Aṣofin *Nigeria* ninu oṣu yi nitoripe ọdun marun ti a ni lati parọ awọn ti nwọn mbẹ nibẹ nisisiyi ṣẹ npe: ọgọrọ awọn ọta rope gẹgẹbi Ọgbẹni wa yi ti wa ni ihamọ nisisiyi, awọn le ṣe gudugbu meje nipa aye ti nwọn rope o fẹ silẹ fun wọn nisisiyi lati ṣe kara hanun lati jẹ ki awọn enia dibo fun wọn: loju wa ero lasan ni irufẹ awọn wọnyi mba ara wọn gba nitoripe a mọ dajudaju pe awọn agbagba ti nwọn nṣẹhin de Ọgbẹni Herbert Macaulay ki yio jẹ ki ẹnikan ṣakala fi iyan ewura gbọn ilu ni ọbẹ danu.

Nilọlọyi ni a ngbọ firinfirin imura ti a gbọ pe awọn kan nmu lọwọlọwọ yi nipa pe ki Ilu yan wọn lọ sinu Ajọ-Igbimọ na, njẹ ọwọ ti awọn ti a nwi yi wẹ ilẹ kọ ni nwọn yio finu bayi? Nitotọ irufẹ awọn ẹni bayi le ma sope awọn dupẹ pe ẹniti iba di nwọn lọwọ fun irufẹ ipo bayi ko si ni ọna, ṣugbọn nwọn gbagbe pe Herbert Macaulay ko ku ara lo fi ti: awọn aṣẹhinde Ọgbẹni yi ki yio fun awọn ti nwọn ko to ila de ti nwọn nfẹ de nipa ni aye arafi kan lati mu ifẹ wọn ṣẹ: Ṣi ọ! irufẹ awọn enia bayi rope ọbẹ tutu o ku ki Adamu ma bula, wọn ko mọ pe Aja lo lẹru iro ni pẹpẹ npa. O yẹ ki awọn ilu mura girigiri lati ma tẹle imọran ti awọn Aṣoju Ọgbẹni Macaulay yio ma bẹrẹ si fun ilu nipa awọn ẹniti ilu yio yan ti ọjọ na ba ko: gbogbo wa ni a nran rogbodiyan ti o wa ni ọdun karun ọhun nigbati a kọkọ yan awọn ẹni mẹta a ha le ṣẹṣẹ ma sọ ti iṣẹ ribiribi ti Ọgbẹni Macaulay ṣe pẹlu awọn ẹmẹwa rẹ ki nwọn to le jori awọn ti nwọn mba ilu sare ije lakoko yi? Nitorina o dọwọ ẹnyin agbagba ilu lati mọ ẁé ti ẹ o wẹ ti ko ni si aye fun awọn ti ẹnyin ilu ko fẹ ki o lọ sinu Ajọ-Igbimọ na: iwa arekereke, iwa arekenda ti awọn ẹlomiran ni lọwọ ti nwọn si nfẹ hu lati lọ sinu Ajọ-Igbimọ na lo njẹ on: ẹnyin ilu ko gbọdọ fun irufẹ ẹnibẹ laye.

Nipasẹ ti ọrọ Eleko, a ti sọ pe idigbolu tabi idalọwọkọ ti Ọgbẹni Macaulay ri lẹnu ọjọ diẹ sẹhin yi ko le di ilọsiwaju ọro ẹjọ na lọwọ: ẹnyin papa sa mọ pe iṣẹ suru ni iṣẹ ọrọ ti o ba ti lọ si kotu ohun ti o ṣoro loju egun awọn ti bo ẹyini ni pe Idajọ Are ti tẹ ilu lọwọ Aṣẹ Ọba *King* si ti tẹ wọn lọwọ pẹlu, ko si ohun meji ti o ku ju pe ki kotu Ganran fi ọjọ si riro ẹjọ na eyiti a si tanma pe ki yio jẹ ohun pipẹ lọ titi mọ.

Lẹkan si a ke si awọn Aṣoju Ọgbẹni Macaulay ki nwọm san ṣokoto giri lati bẹrẹ si iṣẹ nlanla ti o wa niwaju wọn nisisiyi, o yẹ ki nwọn fi ifẹ ti nwọn ni si Macaulay han nipa ṣiṣe oju rẹ daradara ki nwọn ma si fi aye silẹ fun awọn ọta lati yọ ṣuti si wọn pe oju nikan ni nwọn le ṣe nwọn ko le ṣe ẹhin O dọwọ nyin o.

Ki Ikoto ṣe aiye Igbin 're!!!

## AWỌN ALEJO LABẸ ORULE KAN.

O han ni ero gbogbogbo wipe lati bi ọdun mẹwa tabi mẹdogun to kọja, gbogbo awọn okun arede lo nja ni ijakuja. Eyi ki ṣe wipe ka ṣiro rẹ nigba kan si ekeji wipe igbeyawo lailai din ku si ti lọlọyi, ṣugbọn ọwọ ati itunmọ idi bawo ni a ti ṣe fẹ gbeyawo yatọ ni ọgbọn si awon ẹlomiran to ngbe ni lọwọlọwo yi Igbeyawo ti lailai bakanna ni a ngbe ni sẹnyin, ṣugbọn ki ṣe pẹlu ero ti a ni lailai wipe ẹru nla ni mo fẹ ti ọrun bọ yi afi bi Ọlọrun ba mi gbe, ko si ero arojinlẹ bẹ nyẹn ni

loloyi. Awon toko-taya igbani won a ma gbe abe orule kan titi titi àyá fi ti ọlọjọ ba de si arin wọn, awọn pẹlu ọrẹ obinrin ọkọnrin wọn. Ni ọdun diẹ sẹhin, ọkọnrin kan ti o ti gbe iyawo rẹ ni wọn ọdun mejila obinrin to gbe ni iyawo jẹ ara America, o si bi ọmọkọnrin meji fun ọkọnrin yi, ọkọnrin si ṣe iwe ẹbẹ si Kotu nla wipe ki nwọn fa iwe arede wọn ya, nitoripe ohun ti awọn ni lati ṣe ki wọn to gbe arede awọn ko ṣe gẹgẹ bi ofin ti awọn ṣe ipinnu si, Ilu ti a nwi yi nje Scotland, ohun ti ọkọnrin yi nwi ni pe ọkan ninu awọn mejeji ni lati gbe Scotland fun ọjọ mọkanlelogun ki igbeyawo yi to ya.

Ohun to pari ọrọ yi emi ko mọ tabi ki nran ti rẹ nisisiyi, ṣugbọn bi ọkọnrin yi ba jare iwe ẹbẹ rẹ, ohun ti o ṣẹlẹ ni pe, obinrin ti o gbe ni iyawo, ti nwọn si ngbe pọ, fun ọdun mejila ti a si npe, orukọ ọkọ mọ aya lara, ti nwọn si ngbe ni gbangba ati ni ipo ọla pọ gẹgẹ bi aya, ti nwọn si fi otitẹ si, ati wipe awọn ọmọ wọnyi wọn o wa di ọmọ ti ofin kọ. Lati igba ti Romans titi wa fi di ọjọ oni, awọn ọkọwe ọnakọna ni wọn ngbe ọrọ arade gba orişirişi itunmọ ni wọn nfun, won ti npe ni Iṣẹ, gẹgẹ bi ijoko Ọlọla, gẹgẹ bi adehun, gẹgẹ bi onjẹ alẹ Oluwa, gẹgẹ bi igbekun fun isin, gẹgẹ bi ipo ẹni, gẹgẹ bi ohun ti a fi le ni lọwọ fun şişe, gẹgẹ bi ijohun lẹ torọrọ, gẹgẹ bi adehun lati şişẹ tabi lati lanọ dukia. Ilana nla meji lo wa gan. Ekini lọna ofin ti a mọ, ekeji nipa ẹsin. Jẹ ki a mu ẹnu le ekini na :—

Ọpọlọpọ enia lo wa, ti nwọn mọ tabi ti ko ye wọn awon ohun daradara to dun ieti nipa ofin ti a ma şe bere wipe : kini Igbeyawo ? O le fi esi bayi wipe Igbeyawo jẹ idajọ larin ọkọnrin ati obinrin ni tarara nipa ofin rẹ. Itunmo yi jẹ otọ ko si buru, o fi nkan wipe ofin ni arade ati pe ko si igbeyawo lalai si ofin. Şugbọn bi o ba jẹ bẹ, kini a le wi nipa idajọ ti o ti nşẹlẹ lati aiye ba aiye ki ofin to wa de !

Jacob ko gbe Rachæl ni iyawo Isaac ko gbe Rebecca ni iyawo (bẹni wọn si gbe pọ ni ododo) Abraham ko gbe Sarạ ni iyawo (ki a ti ẹ wipe ẹda to yatọ ni Adam) ko gbe Eve ni iyawo, ati pe gbogbo awọn omọ ọkọnrin lati igba ti aiye ti wa, won ni lati bọ si ipo ọmọ ti ofin ko ka kun awọn ọmọ to tọ Suna loju ofin.

AJAGA OFIN.

Bi aşẹ ofin ba jẹ ohun pataki fun igbeyawo, bi igbeyawo yi ko ba le duro lalai si aşẹ ofin, diẹ ninu awọn ti nwọn ti papọ lati aiye ba iye ti nwọn si mọ nipa ọna wọn, idajo won lati igbana ni lati jẹ ti ale, ati iwa agabagebe nipa iwa agbare ti ko şe ohun to lodi si ofin iwa aimọ buruku to wa lọwọ awọn alarede, şugbọn ti ko yoju lode jẹ arede daradara.

Ọkọnrin to gbeyawo nitori owo, ati obinrin to si ba ọkọnrin gbeyawo nitori ipo to wa, awọn yen le jẹ arade ododo, ti nwọn ba si gbe ara wọn larede lọna ofin, bẹni awon ọkọnrin ati obinrin miran lai si ireti ohunkohun, ti nwọn si so ara wọn pọn lalai si ofin awọn yen ngbe pọ ninu ẹşẹ.

Bẹni ki tọ'ọkọnrin to'binrin wa pọ lalai si iwa eri tabi ẹgbin lara wọn, ko si ohun to kan ofin ninu yẹn. Igbeyawo yi jẹ ohun ti ilawọ rẹ han gedegbe gẹgẹ bi eto rẹ nipa ofin. Şugbọn ofin ko ni ohunkohun şe nipa eyiti o ba jẹ mọ ara ẹni ninu, nipa adehun igbeyawo, şugbọn ofin jẹ mọ eyiti o ba jẹ mọ ode gẹgẹ bi orukọ tabi ohun gbigba. Şugbọn idahun si eyi nipa ohun to jẹ mọ ode, loju ofin, nipa igbeyawo totọ wipe lalai si eyi igbeyawo ko si.

Ofin ilu Oyinbo o dabi ẹnipe ko ni opin nipa ọrọ yi, eyi mu wa niran nipa obinrin kan to jẹ wipe ko ni eri kọkan lara, o nba ọkọnrin kan gbe lalai si bojuboju nibẹ (Bi obinrin ba şa wun ẹni bo ti wun ki orukọ obinrin na bajẹ to, ki wọn si fi orukọ rẹ darin tọ ọkọnrin to ba ma ku ti irufẹ obinrin na lọrun ko ni ogun) ọkọnrin to ti fi aya rẹ silẹ ni ọjọjọjọ, nigbati ẹjọ kan wa ya ti obinrin na bọ sinu apoti ẹri, obinrin yi wa daruko ara rẹ bi orukọ ti nwọn mọ si. Ni Adajọ wa ni ma sọ isọkusọ wọn yen nibi Adajọ wipe iwọ ki şe Mrs. So-so-and-so arara şugbọn Miss So and so ati pe ko si şọra lati ma ranti orukọ rẹ ni ọjọ miran.

---

ỌNA AREFO O.

Ọgbẹni E. T. Adewoyin Coker fi Eko silẹ ni ọjọ *Monday* pada lọ si Ile-Ife pẹlu ọkọ Kabọ lọwọ lọ.

---

## *Olusakin's Column.*

BIBLE SUNDAY.

In connection with the 50th Anniversary Celebrations of the Yoruba Auxiliary Association of the British and Foreign Bible Society, Sunday the 26th August last at 9 a.m., observed in all the Anglican, Wesleyan and Baptist Churches as the Bible Sunday when exchange of Pulpits were made among the Ministers of the different Churches Rev. Amos N. Cole Superintendent, Wesleyan Trinity Church, Tinubu, and Rev. Moses O. Dada, Superintendent of the Wesleyan Ereko Church occupied the Pulpits in St. Paul's Church, Breadfruit, and the latter St. John's Aroloya Church, respectively.

Special Services were held in six centres at 7 p.m., viz :—

St. Paul's Church, Breadfruit, *Preacher*—Rev. E. K. Ajai-Ajagbe ; St. John's Church, Aroloya,

### On Leave.

Mr. H. A. Phillips, 2nd Class Compositor, Railway Press, Ebute Metta, has been on a month's leave, as from the 8th August, 1928, and resumed duty on Friday the 7th instant.

---

### Confirmation Of Appointment.

Mr. S. H. Dehumo has been Gazetted as a Senior Attendant, Medical Department, as from the 1st May, 1925.—*Nigeria Gazette* 30/8/28.

Congratulations.

OLUṢAKIN.

---

## ORI IV.

## IṢẸ.

(*Translated from "Character by Dr. Smiles"*).

APA KETALA.

---

Awọn miran ro pe iwa iṣẹ ṣiṣe on ọgbọn abami ko pa ara wọn.

Ninu itan Richard Lovell Edgeworth a sọ nipa Mr. Bicknell kan (ẹniti o ni iwa ṣugbọn ti ko jẹ enia pataki kan, ẹniti a ko mọ ohun kan nipa rẹ tobẹ ju pe o gbe Sabrina Sidney, ti o kọ ẹkọ labẹ Thomas Day, ti o ṣe iwe Sandford and Merton, ni iyawo lọ) pe "laifi ti a mọ mọ awọn ti awọn ti ọgbọn wọn jẹ abami, kun ọwọ rẹ tẹtẹ: o korira iṣẹ ṣiṣe."

Ṣugbọn akajuwe yi ko sunwọn rara. Gbogbo awọn ọlọgbọn abami enia patapata gba, ti ko si ẹgbẹ wọn, ni o jẹ osiṣẹ ti o ju oṣiṣẹ lọ, nwọn ko tilẹ kọ iṣẹ wuruwuru lati ṣe. Ki iṣe kiki pe nwọn ṣiṣẹ ju awọn kan lọ ni ṣugbọn nwọn tun fi ọgbọn ati ifẹ ti o tayọ ṣe iṣẹ. Ko si ohun nla kan ti yio jẹ ajẹbọwaba ti a fi gidigidi ṣe. Nipa suru ati lala lọna ti o tọ ni awọn ọlọgbọn abami fi ṣe iṣẹ ti o jẹ pataki ninu iṣẹ wọn yanri.

Awọn oṣiṣẹ nikan lo ni aiye; awọn ọlẹ ko ni ipa kan. Awọn onișẹ ati awọn alayan enia ni ijọba aiye.

Ko si oṣelu nla kan ti ko jẹ oṣiṣẹ enia. Ani Louis XIV papa sọ pe "Nipa iṣẹ ṣiṣe ni ọba fi ijọba ilu." Nigbati Clarendon nsọ iru enia ti Hampden iṣe, o sọ pe "oniṣẹ ati alakanloju enia ni, ẹniti oṣiṣẹ kan, biotiwu ko to, ko le tẹ lara ẹniti o mọ apade alude tobẹ ti ọlọgbọn ẹwẹ ati omu kan ko le pabo fun mu ati enia ti aya nini rẹ ati iwa rere rẹ ba ara wọn jọ." Ninu lala iṣẹ ti o ṣe pe on ni o yan ara rẹ si, ni ọjọ kan, Hampden kọwe si iya rẹ: "Gbogbo aiye mi lati ọdun pupọ wa, iṣẹ ṣa ni, oni mo nsin Igbimọ ilu nigbati ko si Ọba (Commonwealth) ọla mo nsin Ọba ........ko si aye lati tọju awọn obi mi ọwọn tabi lati ranṣẹ si wọn."

Ni gasikia, gbogbo awọn oṣelu ni akoko Commonwealth (nigbati ko si ọba) ni o jẹ oṣiṣẹ san; Clarendon papa, bi nigbati o wa ninu igbimọ ni, tabi nigbati ko si nibẹ ni, iku iṣẹ ni.

Ẹni itara tabi akanloju kana, eyiti a nri ninu agbara iṣẹ ṣiṣe, ni o mu gbogbo awọn ẹni nla ni igba ti wa di oloruكọ bakana bi ti awọn ti lailai. Nigba rogbodiyan ati bi Ofin-ti a npe ni *Corn Law* wo, Cobden kọwe si ọrẹ rẹ kan pe on "nṣiṣẹ bi ẹṣin, lai ni isinmi kan." Apẹrẹ iku iṣẹ kan ni Lord Brougham; a si le sọ nipa Lord Palmerston pe o ṣe kutupa iṣẹ, yanri nigba ogbo rẹ ju igba ti o wo ni oṣeṣe lọ-ewe iṣẹ, inu-rere ati inu kan ti o ni si ba de opin.

On papa ma nsọ pe wiwa ninu iṣẹ (igbimọ) ilu nibi iṣẹ ja on ja, mu ara on le. Eyiyi gba lọwọ airikan-ṣekan.

---

## KERE O!

Mr. C. B. Shodiya, *Produce Buyer*, ti No. 132, nitosi Niger Company, Ebute Ero, ni ọpọlọpọ Tapo (Tapaulin) siye 15 x 15 fun hihaya, bi o fẹ ṣe ariya ti iyawo lọ sibẹ, bi o fẹ ṣe Wolimọ lọ sibẹ, bi o fẹ ṣe ariya nipa ti oku lọ sibẹ, o wa fun ẹnikẹni ọpọku-ọyọku ni owo hihaya rẹ.

9d. ẹgbẹdogun fun Tapo kan lojumọ.

C. B. SHODIYA,
*Produce Buyer*,
132, Ebute Ero,
Marina, Lagos.

## KINI NJẸ ORILẸ-EDE.

[ LATI ỌWỌ ALATIṢE ]

Lati igbati iwa ti ṣẹ ni a ti ri pe Ọlọrun da ọrun on aiye, ati ohun gbogbo ti o wa ninu wọn' O da ogunlọgọ enia, ẹranko, ẹiyẹ ati ẹja sinu aiye. O fi onikaluku awọn ẹda wọnyi sọjọ si ibi kọkan pataki lati ma gbe, ti a mọ loni bi ilu awọn enia, igbo awọn ẹranko, itẹ awọn ẹiyẹ ati ibu awọn ẹja. O fi awọn kan sọjọ si ibiti o moru pupọ fun ibugbe, awọn omiran si ibiti o tutu, awọn omiran ẹwẹ si ibiti o tutu pupọ.

Olukuluku awọn ẹda wọnyi a ma fi ibugbe wọn taka si ara wọn, ohun ti a ba sa ni ii a taka. Nwọn a si ma fi nani gẹgẹ bi a ti ma ngbọ nigba gbogbo pe—ilu temi dara ju tirẹ lọ; o si fẹran lati ma pe awọn ti ki iṣe ara ilu tiwa ni ara ilu-ki-'lu. Iṣe enia sa ni iṣe ẹranko, mo ro pe bakanna ni yio ri larin awọn ẹranko ati ẹiyẹ, boya awọn ẹja le ma hu irufẹ iwa bayi pẹlu—Ẹlẹda lo sa mọ ohun ti nwọn nṣe ni abẹ omi.

Ko si ohun meji ti o mu ero bayi wa si ọkan ọmọ enia ati awọn ẹda yoku, bikoṣe eto ti a ba ni ode aiye, eyini ni aidogba ti o wa larin ipin ti Ẹlẹda pin fun olukuluku wọn, titi awọn to pọ si ngun wọu loju—ohun ẹni ni sa jọ ni loju.

Nigbati a tun boju wo ode aiye lọ garaga, a ri pe oniruru awọ ni Ẹlẹda da si ara awọn enia, ẹranko, ẹiyẹ ati ẹja; awọ awọn apakan dudu, ti awọn kan funfun, ti awọn omiran pupa, ti awọn omiran ẹwẹ si jẹ ofefe. Bakanna ni a ri i larin eweko igbẹ, ti apakan tutu yọyọ, ti awọn ododo nfi ogo orişirişi awọ wọn han. Ki nṣe ninu awọ ara nikan ni ẹda yatọ si ara wọn—ede ti nwọn nfọ yatọ pupọ si ara wọn pẹlu, ti a ba yọ igi inu igbo ati awọn ẹja inu omi kuro, boya ẹwẹ, awọn wọnyi na yio ni ọna ti nwọn fi nba ara wọn sọrọ.

A o sa le fi oru han, oniruru ede li a ri larin awa enia dudu, gẹgẹ bi a ti ngbọ ni ẹnu ara wa kakiri gbogbo ilẹ wa. Bakanna gan lo wa larin awọn enia funfun, pupa tabi ofefe. Ede ẹnu awọn ẹranko yatọ si ara wọn, bẹ si ni ohun orin ti awọn ẹiyẹ oju ọrun nkọ yatọ leti si ara wọn. Ki isi iṣe bayi nikan, iwa ati iṣe oniruru ni a ba lọwọ awọn ẹda—gẹgẹ bi ti awa enia dudu ti pẹka si pe ọna ainiye—ni orişirişi ọkan-ko-j'ọkan, bakanna gan li o ri larin awọn enia funfun, pupa tabi ofefe. Iwa awọn ẹranko igbẹ yatọ si ara wọn, bẹ si ni ti awọn ẹiyẹ oju ọrun, a si le ro pe bakanna ni ti awọn ẹja inu omi yio yatọ si ara wọn, bi o tilẹ ti jẹ pe ti awọn ẹja ko le da ni loju lati sọ danyin-danyin—nitoripe Ibugbe wọn jinna si wa.

Bayi ni a ri ipin ti Elẹda pin fun onikaluku ẹda Rẹ ni ode aiye, ni orişirişi ọkan-ko-j'ọkan, ti ẹnikini fi yatọ si ti ẹnikeji—ko si ba ara wọn mu. Aiba ara wọn mu ninu ohun gbogbo yi gan ni o mu ki awọn ẹda, lairo o jinlẹ pe awọn ki iṣe ọkanna, niwọn igbati nwọn ko ti da wọn si ori ilẹ kanna. Nwọn gbagbe pe Ọlọrun, Ọkanşoṣo na ni Ẹlẹda ohun gbogbo, ati pe ọmọ-iya si ni gbogbo ẹda jẹ.

---

## IKU MBẸ ALIMUTU.

Tẹduntẹdun ni a fi jihin iku Tairu Animashawun, ti o ṣẹlẹ ni ile rẹ ni Martins Street, ni Alamisi ọsẹ yi.

A ki awọn ọmọ ati gbogbo awọn ebi rẹ nwọn ku afẹku.

---


## INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA



Atupa ti a npe ni "Oşupa mi" jẹ oju-lowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Şango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Orişi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Şabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranşẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

# JUST ARRIVED.

The long expected Zotal, Glaxo, Lactogen, Vapex Kruschen Salts, Hair Dye, Kalzana, Vitafer, etc., etc.

### *Ressurrection of the body.*

Do not remain a victim of chronic weakness, pains in the bones, shortness of breath, shaking of the hands and limbs. Get a bottle of Dr. de Roos concentrated Guittæ Vitæ, it will renew every atom of your flesh into activity and set you along the pathway of longevity. **£2 2s.** a bottle, largest size.

### *If the blood is pure, health is sure.*

Our " Cooling Blood Purifier " purifies the blood of all impurities **7/6d** per bottle. Herb Tea—6d per packet. Native own remedy clears the bowels, purifies the blood.

### Why do experienced mothers like Yaro ?

Because it is a reliable preservative which suppresses infant's suffering during teething period. **2/3d & 3/3d** per bottle.

### *Life Tonic Tablet—A Wonder Worker.*

Life Tonic Tablet contains pure yeast and vitamines and can be taken by men with large or small means. It is a wonder worker. **3/-** per bottle.

### *Wireless Female Pills.*

For all monthly disturbances peculiar to females, use Wireless Female Pills, the latest scientific discovery for female disorders. **4/6d** per bottle. It is an effective fertiliser against barreness Sold only by Iyin Oluwa Medicine Stores.

WE STOCK:—

Back and Kidney Pills 2/6d
Anti-Rheumatic Salt 2|- & 3/6d
Vibrona Wine 7/6d.

*Obtainable at :—*

# IYIN OLUWA MEDICINE STORES

*Head Office* :—88, Broad Street, Lagos,
*Branches* :—6, Martins Street,
41, Alli Street, Faji Market,
100 Griffith Street, Ebute-Metta.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by Victor White, Esq., *The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—Not Obtainable Elsewhere.
"Shake the Bottle."

### AREMO FUN OKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o njẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki jẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price Ten Shillings (10s) per bottle.

*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by Victor White Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B:—Not obtainable elsewhere.*

### GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati oriṣiriṣi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

Price 10/- Per Bottle.
Postage 2/6 extra.

## WHITE'S WOND RFUL BRA N TONC

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq
41, Offin Road, Lagos.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

### EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe ṣiṣẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba ṣe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
Victor White, Esq, *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".

Price Ten Shillings (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

### EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oṣu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aṣẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,
Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specifie acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

*Cable Address* :—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIRẸMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

**Indents House.**

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

**A Trial is Solicited.**

---

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

**TO LET.**

**One Splendid Pleasure Car**

No. L2754.

***Always at everybody's service at Tinubu Square.***

For Terms, Apply to —

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

## ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

## Ni No. 63, Ehingbeti, Eko,

—— : o : ——

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmini ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orișirisi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorișirișị ni aṣetejọ : aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


Printed at "Tika-Tore" Printing Press, 20, Market Street, Lagos, and Published by Adeoye Deniga at 24, Williams Street, Lagos, Writer and Lecturer.